# Irohin Yoruba

NO. 765 — FEBRUARY 3 — FEBRUARY 9. 1960 — Kobo Meji (2D.)


**LAKAYE ỌRỌ**

OJU Oluwa mbẹ lara awon olododo, eti Rẹ si si si igbe wọn.
Oju Oluwa kan si awọn ti nṣe buburu lati ke iranti won kuro lori ilẹ.
Awọn olododo nke. Oluwa si gbọ, o si yọ won jade kuro ninu iṣẹ won gbogbo.

# IYAWO-ONIYIGI OṢU MEJI SALỌ



EKO—Ni ọjọ Abamẹta ti ṣe ọgbọnjọ oṣu ti o kọja yi ni okunrin kan, Kareem Adetoro ti o nṣiṣẹ ni Olu Ile-iṣẹ P.W.D. l'Eko wa sọ fun awọn oniwe irohin "Sunday Express" pe, iyawo on Iyaafin Sidikatu Amọpe Adetoro salọ mọ on lọwọ nigbati o di ọṣu keji ti awọn ti ṣe igbeyawo.

Iyawo ti o salọ yi jẹ ọmọ Oloye Liadi Fashola ti ngbe Isalẹgangan l'Eko, iyawo na si ti nṣe iṣẹ olukọ ni Ile-iwe Ansar-Ud-Deen, Alakoro, Ni Gbọngan Apejọ Ile-iwe na ni nwọn si ti ṣe igbeyawo ninu oṣu kẹwa odun ti o koja yi, igbeyawo na larinrin, o busiya, o le gongo, nwọn daso-ẹbi, ọpọlọpọ awọn ọlọla Eko ni o peju sibe.

Nigbati o si di oṣu kejila ọdun ti okọja yi kanna ni ọkọ ti ibi iṣẹ de ti o si ba ile rẹ ni ofo, iyawo na ti palẹ gbogbo ẹru rẹ mọ laijalaita. Oko na si ti lọ fun awọn ọlọpa ni irohin sisalọ rẹ na ṣugbọn awọn ọlọpa koi ti sọ pe nwọn gburo iyawo na ni ibikan.

## Benson jẹbi, ṣugbọn Adajọ da a silẹ

EKO.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kini oṣu yi ni Ọgbẹni V. E. Crane, Adajọ-Agba Kotu kekere l'Eko da Ọgbẹni T. O. S. Benson, Minista Alamojuto Eto Irohin Ijọba Apapọ Naijiria lebi lori ẹsun ẹjọ ti awọn ọlọpa nba a ṣe pe o yaju si Ọgbẹni J. A. Adefarasin, Adele Adajọ-Agba Kotu Kekere Yaba ni ọjọ kejidilogbọn oṣu kẹwa odun ti o kọja yi.

Adajọ na tokasi i ninu idajọ rẹ pe, iwa ti o buruju gba a, ti ko si yẹ ọmọluabi ni Ọgbẹni Benson hu, ko si tọ rara fun ẹniti o jẹ ọkan ninu awọn aṣiwaju awọn Amofin. O ni on gba ẹri Ọgbẹni Adefarasin gbọ pe, nitotọ, gegebi o ti sọ pe Ọgbẹni Benson yaju si on ni o ri gan an, o si ni ki Benson toro aforijin lọdọ Adefarasin, Benson si ṣe bẹ ẹ, ni Adajọ na ba ba a wi, o kilọ fun un, o si da a silẹ, pe ki o ma a lọ.

## Ọkunrin kan ku iku iyanu

ILESHA.

GBOGBO awọn ara adugbo Igbaye ni Ilesha ni idagiri da nigbati nwọn gburo ibọn kan ti o yin lojiji ninu iyara okunrin kan, Ayantade Akanni, "Jojo" ẹni odun mejidilogoji, nigbati awọn enia rọ-giri de ibẹ, nwọn ba oku ọkunrin na nilu agbara-ẹjẹ nilẹ ti agbara rẹ si ti tuka yan-an-yan-an, nwọn si ba ibọn

Wo oju ewe kẹrindinlogun

## Awọn Aṣoju Ijọba Naijiria ni Ilu Oyinbo



Aworan oke yi ni ti awọn aṣoju Naijiria mẹta, Oloye A. Coker, Aṣoju Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria ni Ilu Oyinbo; Alhadji Abdulmaliki, Aṣoju Apapọ Ijọba Naijiria ati Adele Aṣoju Ijọba Ipinlẹ Ariwa Naijiria ni Ilu Oyinbo ati Ọgbẹni F. O. Ihenacho, Aṣoju Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun Naijiria ni ilu Oyinbo, nigbati nwọn nsọrọ ikini-kuewu ọdun titun sinu ẹrọ gbohungbohun Ilu Oyinbọ, eyiti a gbọ lalẹ ọjọ aisun ọdun titun ni Naijiria.

## Akintọla ni Idibo Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun di 1961

IBADAN.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹdọgbọn oṣu ti o koja yi ni Oloye S. L. Akintọla, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ja irọ awọn alarosọ ti nwọn npurọ pe, ninu ọdun yi ni nwọn yio tu Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ka ti nwọn yio si tun dibo yan awọn aṣoju titun si Ile Igbimọ na. O ni arosọ irọ ni patapata.

Ikede ti o jade lati Ile-iṣẹ Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹdogbọn oṣu ti o kọja ti nwọn fi ṣe alaye fun gbogbo enia lori iwe-irohin meji ti o ndaba pe inu ọdun yi ni nwọn yio tu Igbimọ Ijọba na ka ti awọn oṣelu kan si nyọlẹ ke pe awọn enia pe ki nwọn dibo fun awọn nipe:—

"Aseko ti Ajọ Igbimọ Ijọba Iwọ-Orun ti o wa nibẹ nisisiyi yio pari ni idaji ọdun ti mbọ (1961) ko si ohun ti o le pe ki nwọn mase lo aseko wọn pari ki nwọn to se idibo miran. Nitorina gbogbo ọrọ agbosọ ti awọn alarosọ ntan kakiri ilu nipa idibo wọle Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ni lọọloyi ki iṣe otitọ, arosọ irọ ni gbogbo rẹ."

# Iya-ẹgbẹ kan digbo-lulẹ o ku ninu agbo ijo

ILESHA.

N[illegible]

## Adajọ sọ awọn ọlọṣa meji sẹwọn

IBADAN.

L[illegible]

## Aṣiwaju ẹgẹ NEPU kan fi £400 tanran

PORT-HARCOURT.

N[illegible]






# Akintọla ba Igbimọ Abẹokuta sọrọ



Ki Oloye S. L. Akintọla, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria to bẹrẹ si ba Igbimọ Ijọba Ibilẹ Abẹokuta sọrọ, o kọ yẹ awọn ọlọpa Ibilẹ ti nwọn ṣe ẹyẹ fun wọn wo na.



Nigbati Oloye S.L. Akintọla, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun nba awọn Igbimọ Ijọba Ibilẹ Abẹokuta sọrọ ninu ipade awọn laipẹ yi, awọn ti o joko lẹgbẹ rẹ ni Alhaji D. S. Adegbenro, Minista Alamojuto awọn Igbimọ Ijọba Ibilẹ Iwọ-Orun ati S.O. Shogbamimu, Minista Alamojuto Iṣẹ ati Igbokegbodo ọkọ





O[illegible]

## Ẹka Ẹgbẹ NEPU ko ba Ẹgbẹ alakukọ ṣe mọ nwọn si kan saara si Olaye Awolọwọ

BAUCHI.

N[illegible]

## Malu kan le ọlọpa

ONITSHA.

N[illegible]

MULTIVITE

KORO EGBOGI-IMARALE

fun awọn ọmoge . .





BDH THE BRITISH DRUG HOUSES LTD. LONDON


Itan
Àyan Ati Amọkẹ
By M.Ọlaleye, 2, Okusọlẹ St. Mushin.
Ayan ilu ti mo ra fun ọ ni yi...
Ayan, jẹki nwe gele ki o wa lu fun mi ki n jo
Ngban-gudu-gban ngban-gudu-gban, o ru gele gẹgẹ o ru gele gẹgẹ
Mo ngba fun ọ Amọkẹ
A! Ilu mi ya!
o ko mo pe Nigbati Bẹmbẹ bạ ndun lạdun ju Bibẹ ni 'bẹ

# Akiyesi Awọn Awo Irawọ nipa Ọjọ-ibi

AWỌN nkan wọnyi ni yio ṣelẹ larin ọsẹ yi lati February 7th de February 13th, 1960.

## CAPRICORN
(Dec 21st-Jan 19th)

Ninu ọsẹ yi wa a ṣe awọn iyipada ati awọn eto ti o le. Maṣe binu si ẹnikẹni laseko yi, ma si ṣe ba ẹnikẹni ja.

## AQUARIUS
(Jan 20th-Feb. 18th)

Ayipada yio ṣelẹ ninu igbesi-aiye rẹ. Wa a pinya pẹlu ẹnikan ti o nfun ẹ ni inira lẹnuloloyi, wa a si bẹrẹsi ma a ba enia titun kan lopọ. Wa a ri ere je nipa pe ki o lawọ ni nwọn si awọn enia ati nipa pe ki o ma a ko iwe ti o tọ si ode.

## PISCES
(Feb. 19th-Mar. 20th.)

Lati ibẹrẹ ọsẹ yi titi di ipari rẹ, owo a ma a to ẹ lowo lona iyanu. Sọ ara re nipa ihuwasi rẹ, ọrẹ re atijọ kan le di ota rẹ gan an.

## ARIES
(March 21st-Apl 20th)

Iyipada nipa ọran ẹbi yio ṣelẹ ni ọsẹ yi, yio si fe ya ẹbi ayafi ki o gba bi nkan ba ti wa. Ni ipari ọsẹ yi wa a ri owo gan an.

## TAURUS
(Apl. 21st-May 20th )

B oi ba ngbero lati ra ile yio tete bosi i. Bi o ba ngbero nipa alagba kan, ede aiyede kan yio ṣelẹ titi ipari ọsẹ yi. Ma a ṣe akiyesi igbati nkan ba ṣelẹ ati lati mu awọn adehun pataki ṣe.

## GEMINI
(May 21st-June 20th)

Wa a ri iro kan ti yio mu ẹ ṣe ayipada nipa igbesi-aiye rẹ gbọ larin ọdun yi. Ṣe eto silẹ dada ki o to lọ ṣe isimi tabi ki o to lọ rin irin-ajo. Bi o ko ba jafara ti o ba si ko enia mọra owo pupọ a to ẹ lọwọ lojiji.

## CANCER
(June 21st-July 20th)

Wa a ni iṣoro nipa owo ninu ọsẹ yi. Ẹnikan ti o nfọwọ-ṣọiya nipa rẹ lẹ ja ẹ silẹ. Ma ti se ipinnu kan na titi ti wa a fi ri daju pe o tọ si ẹ lati ṣe bẹ ẹ.

## LEO
(July 21st-Aug. 21st).

Wa a ri ni ibẹrẹ ọsẹ yi pe awọn onirikiṣi kan ntẹnubolẹ nipa rẹ. Ki ọjọ Abamẹta to to, wa a ri i pe edeaiyede fẹ ṣelẹ larin irẹ ati ọrẹ rẹ atijọ kan. Ọrẹ titun kan tio ni yio si ṣe ẹ ni anfani yio tun fun ẹ ni itunu.

## VIRGO
(Aug. 22nd-Sept. 22nd)

Bi o ba ni awọn ti o gbẹkẹle ẹ, ma a ṣe iranwọ fun wọn. Ariyanjiyan kan yio ṣelẹ larin rẹ ati ọrẹ rẹ kan tabi ẹbi rẹ kan. Ki ọjọ Abamẹta (Satide) to to owo pupọ a to ẹ lọwọ.

## LIBRA
(Sept. 23rd-Oct. 23rd)

Edeaiyede kan yio fẹ ṣelẹ larin awọn ẹbi rẹ. Maṣe jẹki o da ọta silẹ. Bi o ba se suru ti o si fani mora ni ibẹrẹ ọsẹ yi, wa a le ṣe atunṣe dada.

## SCORPIO
(Oct. 24th-Nov. 22nd)

Awọn iyipada ti yio ṣelẹ si ẹ ninu ọsẹ yi yio ṣe ẹ ni anfani, wa a ni owo lọwọ. O ko ni tete ri lẹta kan gba tabi ki o ri idaamu nipa ọran ẹbi. Iwọ pẹlu ọrẹ rẹ atijọ kanylo tun bẹrẹsi lo pọ, o le ko iwe kan si ẹ na ṣiwaju tabi ki o fonu si ẹ.

## SAGITTARIUS
(Nov. 23rd-Dec. 20th)

Edeaiyede kan yio ṣelẹ larin awọn ẹbi. Ireti wa fun ẹ ṣugbọn wa a ni iṣoro diẹ nipa owo. Ni ipari ọsẹ yi ni owo yio to to ẹ lọwọ dada ti wa a ri lọ dada.




# Aṣaro kukuru lori àṣọ ẹbi

**Lati ọwọ Iyaafin Odutayọ, Eko**

INU mi yio dun bi Olotu ba le gba mi laye lati fi aṣaro kukuru yi gba awọn onkawe "Irohin Yoruba" ẹlẹgbẹ mi ni iyanju diẹ lori "AṢỌ-ẸBI", aṣaro na si jẹ itaji ẹmi pupọ fun gbogbo wa lọkunrin ati lobirin gbogbo awa enia ilẹ Naijiria, yio si dun mọ mi pupọ bi ẹnyin ti ẹ ba ka tabi ti ẹ gbọ nipa aṣaro yi bi ẹ ba fi ṣe ọgbọn.

Lotitọ, aṣọ ẹbi jẹ aṣọ ẹgbẹjọda ti a fi mba alaṣeyẹ ṣe ariya ajọyọ lori ohun rere ti Ọlọrun ba ṣe fun un, iba ṣe nipa ọmọ-bibi, iyawo-gbigbe ile-isisi, oku-sisin, ẹhin oku yiyi-pada nipa ṣiṣe iranti ku rẹ, ayọ lori jijare-ẹjọ tabi fun ase wiwewu-aisan ati iru nkan bawọnni ti nko le daruko wọn tan.

Gbogbo iwọnyi dara, o dun, o si bade, ṣugbọn Yoruba npa awọn owe kan bayi:—"Ile la nwo ki a to sọ ọmọ lorukọ". "Ṣe bi o ti mọ, ẹlẹwa Ṣapọn". Bi a ti mo la a de, ẹniti ko ni ẹsin ki i de wọn-wọn" itumọ owe wọnyi ni pe, "A ki i ko ele ṣe ẹṣọ". Bi a ba ti mọ ni a njẹ abula,bi ẹkọ rẹ ba gbona ki o bu omi-tutu la a" itumọ si owe kẹta si ni pe, "Ẹniti ko ba ni ẹsẹ SUNMỌMI, ki i sọ pe ki ẹni ti o ba ni ẹsẹ ki o ma lọ".

Ẹnyin ara mi, ẹnyin enia mi, ẹnyin ẹgbọn mi ati baba mi, ẹnyin ẹgbọn mi ati aburo mi lọkunrin ati lobirinọmọ ilẹ Yoruba ti ẹ ti da gbogbo ara de aṣa a mba wọn da aṣọ-ẹbi. Mo fẹ sọ fun nyin pe aṣọ ẹbi dara pupọ lati ma a ba wọn da, ṣugbọn ẹniti aye rẹ ko ba ṣẹku fun ninu ile rẹ ki o maṣe dan an wo lailai. "Ile ni a nwo ki a to sọ ọmọ lorukọ". Tuna-aṣiri ni aṣọ ẹbi fun ẹniti owo jijẹ-mimu ko ba ti ṣẹku fun lati ba wọn da aṣọ-ẹbi. Ẹ dakun, ika ko ma si dọgba, pe o!

Mo fe ki ẹ fi oye gbe iyatọ ti o wa larin awọn ọrẹ'birin meji wọnyi. Ẹnikan ni okowo igba pọnun (£200) ninu ṣobu rẹ, o si nfẹ ere ti Wa, oju ewe kerindinlogun



# IROHIN LATI OKE-OKUN ATI OKE-ỌYA

# Lokọja yọ ayọ itẹdo ọgọrun ọdun



**Aworan oke yi ni ti igbati Ọlọla Gawain Bell, Gomina Ipinlẹ Ijọba Ariwa nfun Mallam Yahaya Muhamed, Baalẹ Lọkọja ni ọpa-oye larin igbati nwọn nṣe ajọyọ ọgọrun ọdun ti nwọn ti tẹ Lọkọja do.**

## Ẹgbẹ Shaki Parapọ Oke-ṣe ipade

WA GHANA.

NI ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kejila oṣu kini ọdun yi ni awọn Ẹgbẹ Shaki Parapọ Oke-okun ṣe ipade Ajọdun kẹtala ni ilu Wa. Ipade yi dun ju gbogbo eyiti a ti nṣe lati ẹhin wa lọ. Ogbeni Mustafa Adetoro (Alaga) ati Alhaji Giwa Abandawaki lọ si ipade na, Lemọmu ilu Wa ni o ṣe adura. Nwọn si tọrọ adura fun Oloye S. L. Akintọla, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ati Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Aṣiwaju Ẹgbẹ Alatako Igbimọ Apapọ Naijiria. Ki Ọlọrun tubọ ma a gbe wọn lowọ soke.

Ohun pataki ti nwọn tun ṣe eto le lori ninu ipade na Mọṣalaṣi Jimọ ilu Shaki ti nwọn ti nkọ lati ọdun kẹwa ti yio si pari ni ọdun yi ati Ile Ẹkọ-Giga Ijọ Onitẹbọmi "Baptist College" ti eto rẹ ti fi idimu lẹ ati ọpọlọpọ eto imoran ti yio mu ki ilu Shaki fi ni idagbasoke. Ọpọlọpọ awọn aṣoju ni o wa lati igun mẹrẹrin ilu Ghana ati lati ilẹ Faranse. Nwọn si mu ipade na wa si ipari pẹlu alafia. Nwọn si fi ọjọ ipade ti ọdun ti mbọ si ilu Boligatanga ni ọjọ kejila oṣu kini ọdun ti mbọ (1961).

Lẹhin ipade na ni nwọn lọ ki Ọlọla Seidu Ọba ilu wa, Ọba na si ṣe aponle wọn pupọ, o si gba wọn lalejo lọwọ-tẹsẹ si afin rẹ, o ṣe alaye igbati o ti fi nṣe akọwe Kotu Ijọba Ibilẹ ninu ọdun 1937. O si gbadura fun ilọsiwaju ilu Naijiria.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn aṣoju ti o wa ni awọn Ogbeni Mustafa Alaga (Tamale) Alhaji Aileru Abandawaki, James Oni (Niamey Niger), Ẹnlọwọ Alufa A. B. Togun (Shaki) Yesufu Ọrẹdẹgbẹ (Akọwe Shaki Parapọ) Salawu Ajiṣebiegba, James Adelakun (Salaga) J. R. Adejumọbi (Niamey Niger) Lawal Adegoke (Yendi) R. A. Ọlabiyi, Gbadamọsi-Bing (Tamale) Yesufu Ladokun (Yendi) Tijani Akande (Wa) John Popoọla (Kurugu) Yesufu Alabi (Wa) Fasasi Ọlatubosun (Boligatanga) ati Raimi Oyekunle (Sokogun).

Aṣeyi-ṣamọdun o.

## *Adajọ sọ ẹniti o ji agbada ṣẹwọn oṣu mejidinlogun*

KADUNA.

LẸNULỌLỌYI ni Adajọ Kotu Ijọba Ibilẹ Kaduna sọ ọdọmọdekunrin kan, Musa Yola ti awọn ọlọpa pe ni "ọrẹ wa" si ẹwọn oṣu mejidinlogun oniṣẹ-aṣekara: nitoriti o jẹbi ẹjọ ole ti awọn ọlọpa ba a ṣe pe, o ji Joseph Ayanwale kan ni agbada nla kan.

Awọn ọlọpa sọ fun Adajọ pe, ọdaran na wọ inu iyara Joseph lọ ni aṣalẹ ọjọ kan nigbati o ri i pe, o (Joseph) nsun lọwọ lojude rẹ, o si ji i gbe ni agbada nla kan lọ.

Nwọn ni abule Tundun Wada ni awọn gbẹ ti ri i mu pẹlu agbada na ni ọwọ rẹ.



**Aworan oke yi ni ti igbati Ọlọla Alhaji Abukar Tafawa Balewa, Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria, mba Ọlọla Gawain Bello, Gomina Ijọba Ipinlẹ Ariwa sọrọ nibi ajọyọ ọgọrun ọdun ilu Lọkọja. Awọn ọga 0nişẹ Ọba ati awọn 0nişẹ Ọlọrun ni o duro lẹhin wọn.**

## Adajọ sọ abiyamọ ole kan sẹwọn oṣu mejila

OKENE.

LẸNULỌLỌYI ni Malam Saliu Sare, Adajọ Kotu Ijọba Ibilẹ (N.A. Grade 'B' Court) Okene ni ki ọdaran abiyamọ kan ti ọlọpa pe ni onibara wọn lẹ ṣe ẹwọn oṣu mejidinlogun: nitoripe o jẹbi ẹjọ ole ti awọn ọlọpa ba a ṣe pe o ji orişirişi aṣọ Yesufu Işelọ ni Adugbo Orekesu ni ọjọ kẹwa oṣu kini ọdun yi. Adajọ na sọ ninu idajọ rẹ pe ọdaran na ti o ni on ko jẹbi ko abuku ba awọn obirin ni.

## AKIYESI FUN ONKAWE

**Eyi ni lati sọ fun nyin pe, ẹnikẹni ninu ẹnyin onkawe ti o nkọwe si Olotu Iwe Irohin Yoruba ti ko ba fẹ ki iwe on sọnu ki o ma a kọ ọ taara si ile işẹ rẹ ni:**

**Amalgamated Press Ltd.,**
**5/7, Apọngbọn Street,**
**P. O. Box 163, Lagos.**

